# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No. 700 THURSDAY MAY 21, 1964 (2 D)


## Obinrin Kan Ju Ọmọ Rẹ Si Gọta !

IBADAN:— Gbogbo oju titi lo kunṣọṣọ ti awọn mọto ko si ri ọna kọja fun odidi wakati meji nigbati ogunlọgọ enia sare de lati wa wo ọmọdebinrin kan ti nwọn gbe ju sinu gọta ni eti ile iṣẹ awọn afiwe-ranṣẹ (Posts and Telegraphs) ni kutukutu owurọ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi.

Ẹniti ọrọ na ṣoju rẹ ṣe alaye fun oni we irohin wa pe, nigbati on ti duro ni ode niwaju ile on ni on ti ngbọ ẹkun ọmọ na ti o nke pẹlu agbara, ṣugbọn on ko tete mọ pe ninu gọta ni ọmọ ti nke.

Nigbati ọmọ nke, ti ko si dakẹ ni on wa sunmọ ibiti igbe ẹkun na ti njade, nigbati on si yọju sinu gọta, ni on ba ri ọmọ tuntun kan ninu gọta na ti o tun nke.

Lẹsẹkẹsẹ ni on ba lọ si Teṣan awọn Ọlọpa ti on si sọ ọrọ na fun wọn. Lojukanna ni awọn Ọlọpa ti gbe mọto wọn tẹle on wa si adugbo na. Nigbati awọn debẹ, ti awọn Ọlọpa ri ọmọ tuntun na ni nwọn ba sare gbee lọ si Ile-IwoSan Ade Ọyọ fun itọju ṣugbọn ọmọ na ku lẹhinti nwọn gbe de Ile-Iwosan.

Irohin awọn Ọlọpa fi ye wa pe, omi gọta rọ si ọmọ na ni imu, o si ti mu omi gọta yo ju bi o ti yẹ lọ.

A gbọ pe nwọn nwa iya ọmọ na, ti nwọn ba ti ri i ẹo tun ma a gbọ o.

# IJỌBA IWỌ ORUN YAN OYEBỌLA NI ỌBA IṢẸYIN

IBADAN:— Ni kutukutu owurọ ana ọjọ ọjọ'Ru ti iṣe ogunjọ osu yi ni irohin kan wa ninu ile iṣẹ wa pe. Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti fi ẹwọ si iwe aṣẹ ti o wa lati ile iṣẹ Minista Alamojuto eto awọn Ọba ati Ijoye pe, Ọmọ ọba Muṣitafa Oyebọla ni Ọba Iṣẹyin tọ si.

Gẹgẹbi irohin ti o tẹ wa lọwọ ni owurọ ana lati ọdọ oniwe Irohin wa, o fi ye wa pe, nigbati ile iṣẹ Minista Alamojuto eto Oye ati Ọba fi iwe aṣẹ na ranṣẹ si Ijoba, nwọn ṣe apero lori iwe na Gomina Ipinlẹ na, Ọ ọla Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi, fi ọwọ si iwe aṣẹ Oye na loruko Ijọba.

Lẹsẹkẹsẹ ni Ijọba ti fi iwe aṣẹ na ranṣẹ si awọn Afọbajẹ eto Oye ni ilu Isẹyin fun itẹwọgba.

A gbọ wipe ni irọlẹ ana ni iwe aṣẹ ti de si Isẹyin ti o si ti bọ si ọwọ awọn Afọbajẹ.

Irohin na fi ye wa pe; gb gbo awọn afọbajẹ na ti nwọn wa ni ile ati oko ni nwọn ti ranṣẹ si ara wọn lati ṣe ipade lori iwe aṣẹ na ni irọlẹ oni Boya lati gba iwe aṣẹ na tabi lati kọ ọ.

Irohin fi ye wa pe, ti awọn Afọbajẹ na gba, a jẹpe nwon o da ọjọ ti nwọn o ja ewe oye le Ọgbẹni Musitafa Oyebola loni, bi won ko ba si gba, nwon ( da esi iwe ra pada lo si ile iṣẹ Minista Alamojuto eto Ọba ati Ijoye fun Ipinlẹ na ki o to di ipari ọsẹ yi

Onirohin wa kan ran waleti pe, ni ojo Aje ti Iṣe ogbonjo osu kiul odun yi ni Ijoba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria yọ Ọba Alayeluwa Ọba Raji Adebowale ni Ọba, nwọn si tun le e jade kuro ninu ile Iṣẹyin ti jinna sii

Ikede ti o jade ninu Ile Iṣẹ Alakoso Ijọba nigbana ṣe alaye wipe awọn rọ Ọba na loye, awọn si le kuro nilu lọ si Ebute kan Irele ni agbegbe Okitipupa leti odo kan ti nwọn ti npa ẹja.

Ninu alaye Iwe Ijoba, iwe na tun ṣe afikun nigbana pe, awon le Ọba na kuro lori Oye nitori ki alafia ati Ijoba rere o le wa fun awon enia gẹgẹbi ifẹ okan awon ara ilu Iṣẹyin.

Lẹhinti Ijoba ti gba imọran ti nwọn si tun fi oro ha han Igbimo awon Ọba Ipinlẹ Iwo Orun Naij ria, ni nwon to dawọle eto yiyọ lori oye na.

Lẹsẹkẹsẹ ti Iwe aṣe na ti jade ni Ibadan ni ọjọ na, ni awọn Ọlọpa ti ṣogba yi ile Ọba na ka ti won si fi iwe asẹ han pe ki o tete ma a palẹmon nitoripe ko ni sun ninu Afin rẹ ni ojo na, wọn si ko gbogbo ẹru rẹ sinu moto lo si Ebute Irele ni ibiti wọn sọ pe Ọba na yio ma gbe titi di ojo iku rẹ Lati igba na ni awon Alasẹ Ipinlẹ Iwo Orun Nigeria ti yan Igbimo oluwadi kan lati wadi ona ti won gba fi Raji Adewale jẹ Oye ni oṣu kẹrin Ọdun ti o koju yi

Ko pẹ pupọ lẹhin eyi ti awọn Igbimo Oluwadi wa fi wadi ọrọ na ti nwọn si nronu lati gbe ipinnu wọn lori iwadi na jade, ṣugbọn titi di isisiyi, Igbimọ na ko ti gbe iwadi wọn jade.



Ọba Alaiyeluwa Raji Adebọwale
*Ọba Aṣẹyin ana.*

Onirohin wa Ejon'gboro ti o lọ wo Ọba na nibiti nwọn gbe lọ fi ye pe, enia mesan lo ba Ọba na jade ninu ilu ti nwon si nlọ ba gbe ni Ebute na.

Ninu awọn enia na ni iyawo rẹ marun wa, awọn ẹgbọn ati aburo rẹ Nigbati oniwe irohin wa bere lọwọ Ọba Raji Adebowale bi o ti ṣe ngbadun Ebute na si.

Ọba Raji Adebọwale fi ye oniwe irohin wa pe awon ẹfon ti o njẹ on nibiti Ijọba 'gbe on wa yi ko ṣe fi ẹnu sọ.

O tun ṣe alaye fun oniwe irohin wa pe, lati ọjọ ti on ti de ile aiye, on ko ti ri iru awọn ẹfọn ti mbẹ ni Ebute Irele ri. O ni awọn ẹfọn na tobi ọmọ-eṣinṣin.

Nigbati oniwe irohin wa Ejongboro bi Ọba na lere bi o ti lọ ra oogun ẹfọn, lẹsẹkẹsẹ ni Ọpa na ka agbada rẹ soke ti u si fi apa rẹ han oniwe irohiu na, gẹgẹbi igbati KURUNA mu enia, bẹ ẹ ni gbogbo ara Ọba na ri.

Ile na kanṣoṣo lo wa ni Ebute na, ko tun si awọn ile miran nibẹ tabi ni agbegbe ile na.

Nigbati Oniwe irohin wa ṣe akiyesi pe awọn agbalagba nikan ni on ri, ni o ba bere lọwọ Ọba na nibiti awọn ọmọ rẹ wa.

Ejongboro: " kabiyesi, mo ṣe akiyesi pe nko ri awọn ọmọ nyin tabi e ko ti bimọ ni ?

Ọba: Mo ti bi ọmọ?

Ejongboro Nibo ni awọn ọmọ nyin wa?

Ọba Gbogbo wọn wa ni Isẹyin.

Ejongboro: kini ṣe ti ẹ ko mu awọn ọmọ yin wa?

Ọba: ti mo ba mu wọn wa ko si ile iwe ti wọ yio lọ.

Ejongboro: Bawo ni ẹ ti se ngbadun ibi yi si

Ọba : ko si igbadun kan nibi ju iya ati ipọnju ti ijọba nfi oju mi ri lọ"

Iyawo Ọba na sọ fun Oniwe Irohin wa pe ko si ọja nitosi, Ọja ti o w an agbegbe na jinna to ibusọ kna, ko si si moto lati lọ si Oja na

Ijọba ti fi aṣẹ si i pe ki nwọn jẹ Ọba miran ẹniti Ijọba si yan gẹgẹbi Ọba Isẹyin nisisinyi ni ọmọ Oba Musitafa Oyebọla.

Oniwe irohin wa yio lọ si Isẹyin laipẹ yi, ẹ o si ma a gbọ ọjọ ti nwọn o ba jẹ Oye na, ati Ipinnu ti awọn afọbajẹ ba ṣe ninu ipade ti nwọn fẹ ṣe ni Isẹyin loni.

**Dokita Obi So Pe:**

# Akintola Sunmo Awolowo Nipa Oro Oselu

EKO:- Olori egbe Danamic Party ni ile Igbimo asofin Ipinle Ila Orun Naijiria Dokita Chike Obi so ni ile ejo giga l'Eko ni ojo ojo'Bo ti ise ojo keje osu karun odun yi pe Oloye S. L. Akintola ti o ti je igbakeji olori egbe Afenifere tele ti o fun jeol ri egbe Demo (NNDP) nisiyi suumo Oloye Obafemi Awolowo ju on lati soro nipa eyi to jemo oro oselu.



Oloye S. L. Akintola

Dokita Obi si tun so ni edakeji ewe pe on si le ba oloye Awolowo soro to jemo ti oselu nitori egbe on ati egbe oloye Awolowo AG si gbo oro enu ara nwon.

Dokita Obi nso eyi nigbati o dahun oro lati enu Agbejoro Ijoba to ngbenuse fun ogbeni Moses Chukwuma ti o je igbakeji oga olopa eniti Dokita Chike Obi nfe gba (£25,000) lowo re fun esun ti Dokita Obi fi kan ogbeni Chukwuma pe esun ti nwon fi mu on mo oloye Awolowo ati awon yoku pe on fe doju Ijoba Apapo dele ati pe ninu ti nwon mu on ko si tona rara.

Agbejoro fun Dokita Obi Oloye Rotimi Williams so pe ni ile ejo pe nwon mu Dokita Obi ninu ogu kokanla odun 1962. Dokita Obi si tun so si pe ni ojo kokanla osu kesan 1963 pe titi nwon si fi se idajo ba pe nwon si da on di to sinu ogba ewon fun osu merin.

ASOJU ILU

Dokita Obi si tun so pe on ko ba awon edaran yio ku papo rara lati gbogun ti Oba Binrin tabi ki on ba enia kan gbero lati doju Ijoba dele tabi ki on se nkan to je pe o lodi si ofin ki o to mu on. Dokita Obi si tun so pe on ko si ba enikankan gbero lati gbogun ti Oba Binrin rara.

Ariwo enia ta ninu ile ejo giga na nigbati Agbejoro ijoba Ogbeni Jinadu nbere oro lowo Dokita Obi ti o si pe ni "Ogbeni Obi" ti o si bere lowo re pe nje o mo Ogbeni Chukwuma gegebi Olopa?

Dokita Chike Obi wo oke o si tun wo ile o si so bayi pe "toto re" o si tun so pe on ko ni dahun Obi.

Ogbeni Jinadu sese wa pe ni "Dokita Obi" o si tun bere ibere na lowo re. Dokita Obi si dahun bayi pe on ko mo Ogbeni Chukwuma gegebi Olopa ati pe on sese mo gegebi Olopa nigbati ejo idite si si ijoba bere.

Ogbeni Jinadu si tun bere lowo Dokita Obi pe nje o mo pe awon Olopa je asoju fun ilu? Dokita Obi si dahun pe on ko mo pe Ogbeni Chukwuma pe Olopa nigbati o wa mu on ni ona ti ko to. Dokita Obi si tun so pe ki ise otito ni awon Olopa mu on ni Idiroko ati pe awon Olopa mu on ni Ogba awon Olopa inu ni Eko ati pe Olopa Oyinbo kan lo si mu on.

Ogbeni Jinadu:- Nje ki ise iwo pelu Oloye Anthony Enahoro ni awon Olopa mu ni Idiroko ninu Odun 1962? Dokita Obi:- Nwon ko mu mi ni Idiroko ati pe



Oloye AWOLOWO

mo si ba Oloye Enahoro de Idiroko.

Jinadu:- Kini se to ba Enahoro de Idiroko nigbati o fe sa lo.

Dokita Obi:- Emi ko pelu Oloye Enahoro nigbati o fe sa lo igba kan soso ti mo ba Enahoro de Idiroko ni igbati o fe rin irin ajo kuro ni Naijiria. Dokita obi si tun fi ye ile ejo pe on si ba Enahoro se itoju ati bi awon ijoba yio se gbe ontele iwe eri irin ajo re nitoripe Oloye Enahoro je ore Dokita Obi.

Nwon si tun bere lowo re pe nje o mo pe oloye Enahoro pelu eniti o fe gbo gun ti Ijoba? Dokita Obi si dahun pe on ko mo rara

Dokita Obi si si so pe on nlo ma nki oloye Awolowo ati Enahoro nigbagbogbo ati pe on ko lo si ile oloye Enahoro larin ojo meji si meta ki o to di pe nwon nwa oloye Enahoro.

Jinadu:- Larin igba ti o fo nki oloye Awolowo nje e ko ba nsoro nipa oro to jemo ti oro ilu?

Dokita Obi:- Mo si ba oloye Awolowo so oro to jemo oro oselu sugbon olo



Dokita Chike Obi

ye S. L. Akintola to je igbakeji olori egbe Afenifere nigba na sen mo oloye Awolowo lati soro nipa oro to jemo ti ilu.

Jinadu:- O si ba Oloye Awolowo soro nigbati o wa ni ihamo ni Ikoyi?

Dokita Obi:- Beni sugbon oro to jemo ti Ilu bawo? Clement Nageen De Lasting Adajo agba ti Eko pe ibere na ko ye on. Adajo na si so fun pe Agbejoro si nbere lowo re pe oro to ba ti jemo ti ilu Dokita Obi si so fun pe on ba oloye Awolowo to jemo ti oselu ati pe egbe on nfe isowopo pelu oloye Awolowo. Dokita Obi si tun so pe nwon si fi esun nkan Mumu ni O si tun so fun ile ejo pe nse ni nwon si gbe ejo na lo kolu gaaran ti Onisha ti nwon si ni ki o lo si ewon osu meta tabi ki o san poun marundinlogbon owo itanran o si tun so pe eleyi sele nigbati awon olopa nse iwadi ti esun igbogun ti Ijoba

Dokita Obi si tun so pe nwon ko mu on fun esun kiko nkan to lodi si ofin ati pe nwon mu on fun ti te nkan to lodi si ofin.

Ogbeni Moses Chukuma si tun so ni ile ejo na pe, Ogbeni John Lynn ti o je igbakeji olopa inu lo ran on lati lo mu Dokita Obi ati pe awon odaran ti nwon mu fun esun igbogun ti Ijoba yio si ti ara han ni ile ejo ni owuro ojo keji. Ogbeni Chukuma si tun sosi pe ni ojo kankanla osu kesan odun 1962 pe nwon ni ki on lo fun ayewo awon ohun ose kan to lodi si ofin ni Apapa. Ogbeni Chukuma si so pe ni ojo kokandinlogun osu kesan odun 1962 ni nwon si fi esun kiko ohun ose wo ilu Dokita Obi ni Onisha. Osi tun so sii pe ni ojo kejilelogun osu kesan odun 1962 ni nwon si ran on lati mu Dokita Obi lose ile ejo lati lo je ejo.

Ogbeni Chukuma si so ni ile ejo pe nigbati nwon nse ejo Dokita Obi ti on si so pe nwon ko gbodo gba iduro fun on Chukumu pe on ni se pelu on la pe ojo Nigbati agbejoro fun Dokita Obi Oloye Williams bere oro lowo ogbeni Chukuma o si so pe awon olopa Idiroko so pe nwon mo Dokita Obi nigbati o ngbiyanju ati

Wo Oju Ewe Karun

# IWE SI OLOTU

## Shomolu nfẹ ile Iwosan nla

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye lati ke si Olotu Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Nigeria lati fun ilu Shomolu ati agbegbe rẹ ni ile iwosan nla eyi si jẹ ọkan ninu ohun to ntẹ awọn ara ilu yi ati agbegbe wọn.

Eyi si jẹ ohun abuku lati ri pe ti aisan to tobi kọlu enia ti olu wa rẹ ko to le de ile iwosan oluwa rẹ yio de Eko tabi ki o lọ si Ikẹja ati ilu Shomolu ko kere rara. Inu mi yio dun bi Ijọba Iwọ Orun bale gbiyanju gidigidi lati fun ilu Shomolu ni ile iwosan ati pe eleyi ko sile jẹ ohun iya lẹnu fun awa ara Ilu Shomolu nitori ti igba kan ti wọn ti ṣe ileri fun wa pe wọn yio fun Shomolu ni ile Iwosan nla ọna



Oloye S. L. AKINTỌLA

ọlọda ṣugbọn ko si ikan-kan t wọn se ninu rẹ. A o ma reti es ileri yio.

Emi ni
K. A Olowu
Shomolu

ọna ilu na lo si ba jẹ pupọ ju o Modupe o olotu

Emi ni
Joseph
Shomolu,

## Adupẹ Fun Ilu Ijọmu

Inu mi yio dun pupọ bi olotu ba le gba mi ni aye ranpẹ ninu Iwe rẹ ti nkọwa ni ni ọgbọn ati oye lati dupẹ lọwọ awọn Ijọmu-Oro lọkunrin, lobinrin lọmọde ati lagbalagba fun ami ifẹ ti onjape larin wọn, si ni ifọkantan arawon.

Mo dupẹ lọwọ baba wa alagba Alhaji Momọdu Adekaruju, Alhaji Yesufu Ajiboye ati Alhaja iyawo rẹ, adupẹ ti Ọlọrun ṣe awọn ni alalọbọ, ẹ ku sẹ Oluwa o, Ijọmu-Oro y o gbe nyin amin

Bi ẹ ti de yi, ẹmọ jẹ ki o rẹ nyin lati tun mọ wa alafia ilu wa nitoripe bi ile ko ba gun aiya ko ni balẹ rara.

Nigbati aba ni ifẹ si ara wa nigbana ni a oto le moju to ilu wa, awọn nkan ti a nfẹ yjo wa ẹ wa lọwọ, ilu wa na yio wa jẹ ọkan ninu awọn ilu nla to tun ni okiki ni Ipinlẹ Ariwa.

Mo dupẹ fun aye ti ẹgba mi olotu iwaju ni opa ẹbiti nyin yio ma re si

Emi ni,
R. A. Oladipọ
Ijọmu—Oro

## A Nreti Eyi

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye lati ke si Olotu Ijọba apapọ lati tete tẹ esi iwadi ti mogan nipa eto fun ẹkunnwo fun awọn oṣiṣẹ Ilọ Naijiria.

Eyi si jẹ ohun iyalẹnu lati ri pe leto iwadi na si tipẹ pupọ ju ati pe inu awa oṣisẹ yio dun bi Ijọba ba le ṣe gẹgẹbi a ti nro pe eto iwadi na yio ri.

Ninu awọn nkan ti a tun nreti ni gẹgẹbi Olotu apapọ yio ṣe lo ipo rere ti yio eto nipa enia kika to mu ariyanjiyan wa fun awọn papa julọ fun awọn enia Ipinlẹ Ila Orun ati Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria ti nwọn sọ pe nwọn ko fi ara mọ eto enia kika na.

Ki iṣe Ipinlẹ na nikan bi ko se gbogbo awọn enia Naijiria. Mo dupẹ o Olotu.

Emi ni
A. Olu Johnson
LAGOS.

## Itirẹ Nkọ

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye lati ke si awọn wolewole ilu Mushin lati ṣe abojuto ilu Itrẹ. Itrẹ si jẹ ilu kan to si buroju ati pe nkan to fa eleyi ni pe awọn to je alalaso eto ilera ko ṣe itoju ilu na rara ati pe ọpọlọpọ awọn wolewole ti o je pe o na nlo si bọ ki iṣe nwọn gẹgẹbi iṣe ati owo si ti ba awọn wolewole na je pupo ju Inu wa yio dun bi yoba ibile ilu Mushin ba le ṣe ibẹwo ilu na ko nwọn le mo gegebi ilu Itere na se buru bi. Ati pe ni asiko ojo yi ilu Itirẹ ko ba oju nun rara aruo ilu titi de awọn

# Ema Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

## Iyipada Ile Isẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti wa si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan ki o wa si ile itaja wa ni Nọmba 1, Ishiba Street Odo Eran Itirẹ

## Apejuwe Ile Isẹ Wa

Ẹ Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ti oba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ransẹ fun ọja rẹ Adirẹsi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O WA FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igba Arun | 20/- |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan | 25/- |
| Iwe Ala lati ọwọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara ati Etutu | 20/- |
| Iwe Ilana Yanrin titẹ ati Etutu Şişe | |
| Iwe Afọsẹ Isẹdalẹ Yoruba ati psalmu Ajẹbidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Iṣẹgun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 10/6 |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/- |

J.O. Sho
c/o Postal yinka
Itirẹ Via Suru Agen
Yaba Lere,

1 —Ishiba Street (Odo Ẹran)
ITIRẸ


BI O BA NI

Iwe—Titẹ

FUN

Lilo nibi Işẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku

ATI

Iwe gbeyawo

TETE KỌWESI ILE—IŞẸ—ẸRỌ ITẸWE

Modupẹ Printing Press

16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO POKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA

Dan wa wo lẹẹkanşoşo ki o ri iyatọ


## Egbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Ayie ni ọjọ kẹrinlelogun oşu karun (24/5/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Ba gbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.
Ki ẹ tete de o

LATEEF BABALỌLA
Akọwe Agba

# Awọn Ọlọpa Ṣe Iranti Ọlọpa Egbẹ Wọn To Ku Iku Jamba Mọto

IBADAN:— Awọn Oga Ọlọpa ti Ibadan ṣe iranti ọkan, ninu awọn Oga Ọlọpa to ku laipẹ yi ninu ijamba mọto Ọlọpa na ni igbakeji ọga Ọlọpa Abiak Okon, ẹni adọta Ọdun.

Ọgbẹni Okon si ku ninu ijamba mọto to ṣẹlẹ si Ọlọpa na ati mọto akero lan lọna Shagamu si Ibadan lati lọ si Eko.

Larin eto ẹyẹ iranti ti awọn Oga Ọlọpa jankan-jankan ṣe fun Ọlọpa na eyi to si jẹ pe Oga awọn Ọlọpa agba Ọgbẹni J. S Bell lo si wa niwaju awọn Oga Ọlọpa yio ku ti awọn to yi posi Ọlọpa na ka nigbati nwọn gbe nṣere idaraya.

Gbogbo awọn Ọlọpa na lo si duro gbọingbọin lati fun Ọlọpa na ni ateri ba Ikẹhin, Gẹgẹbi awọn Oga Ọlọpa na ti duro gbọin-gbọin ni nwọn si nfọn isere pẹlu Orin idagbere fun un.

Lẹhin ẹyẹ idagbere yi ni nwọn si gbe Oku Ọgbẹni Okon lọ si Oron ni agbegbe Kalaba ni Ipinlẹ ila Orun Naijiria lati lọ sin Oku rẹ.

Awọn Ọlọpa si mu oni mọto ti on pẹlu mọto Ọgbẹni Okon jijọ pade ti o si pa Ọkunrin Ọlọpa Ṣugbọn awọn Ọlọpa ko ti fi ẹsun kankan kan nṣe ni nwọn si fi si itimọle.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 21 - Feb 19) Ọro isoke ẹdẹọrẹ rẹ yio jẹ ohun ẹdun fun ọkan rẹ, maṣe gbe ọrọ na le ọkan rara.

PISCES (Feb 20 - Mar 20) Agbara awọn ọrẹ rẹ ati jọ yio pọ loni. Iwọ yio si tun bẹrẹsi ko awọn ọrẹ titun jọ.

ARIES (Mar 21 - April 20) Ọrọ nipa ẹbi tabi ọrẹ yio ṣẹlẹ iwọ o si gba alejo kan loni, inu rẹ yio si darujọ-o loni.

TAURUS April 21-May 22:- Idẹra ni ọjọ oni jẹ fun ọ larin awọn ẹbi rẹ awọn ọdọ larin awọn ẹbi rẹ yio ma ṣe ere gele pẹlu awọn obinrin.

GEMINI May-23 July-22:- Iwọ yio ni iranlọwọ lọnakọna ninu idagbasoke iṣẹ rẹ pataki larin awọn ọrẹ ohun ayọ kan yio ṣẹlẹ nigba aṣalẹ ti yio mu inu rẹ dun.

CANCER June-22-July22 Wahala ile ko ni jẹki o joko sibi kan, ọjọ iranti ni yio si jẹ, suru ni opin rẹ bi aba nfẹ ki ile roju ki ọna laye.

LEO July 23-Aug 22 Awọn alajọnu yio bo aṣiri rẹ nipa iduro sinsin rẹ ohun ayọ kan yio de si ọ wa ayẹ lati simi tabi ki o fi ara lelẹ.

VIGO (Aug 23-Sept 22) Orun alafia yio tan lori awọn ẹbi re loni, Alejo kan yio wa bẹọwo ere ayọ yio si de ṣugbọn maṣe yọ ayọ poro.

LIBRA (Sept 23 Oct 22) Maṣe ro ti ara rẹ nikan, ro ti ẹlomiran pelu tirẹ, mura silẹ ohun iyanu kan yio desi arin awọn ẹbi rẹ, o yẹ ki ọlọ ọgbọn ori rẹ nibẹ.

SCORPIO (Oct 23-Nov22) Ayọ ati irẹpọ yio wa larin awọn ẹbi rẹ loni, bi ọjọ ti nlọ siwaju bẹ ni idagbasoke ngberu si larin awọn ẹbi rẹ.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Ayipada titun yio ṣẹlẹ larin awọn ẹbi rẹ, irẹpọ yio gbilẹ larin nyin jọjọ, yio si dabi eyiti ẹ da ẹgbẹ silẹ.

CAPRICORN (Dec 23-Jan 20) Alejo kan ti o mbọ wa ki ọ loni yio wa pelu inu didun ati ayọ


# Congreves Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin Foba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ekọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹduda ara tabi aikoto ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun ara atinu wa ni o ma nfa oyi - oju Ilaogun ati ẹsẹ ara sisọn, ẹfọri tabi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo O b i n r i n gẹgẹbi Ajo fun ilera ati oriṣiriṣi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI OỌ TI WỌN NPE NI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Oriṣiriṣi rọbirọbi egbogi ti wọn ko wa sisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orere lukuluku onigbameji tabi a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi dangu ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ apo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti ọna-ọfun didun, ati oriṣiriṣi omiran pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA **"DYNAMIREN"** TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gogbo



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa ta ọkan losan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradarawọ iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti koja Ọgbọn ọdun ọ si ded adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfe lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọjọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹ rẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pelu. Igbadun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu:-

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street, Lagos.

# Ẹ Gbadura Fun Ọmọ Nyin

Ọrọ irc, [illegible] ma a ko ire ba ọmọ enia. Ọrọ buruku, a si ma a kọ ibi ba ọmọ enia Ẹni eṣu ni i ma a sọ isọkuso tabi ọrọ buburu. Bi awọn ọmọ wa ba ṣe wa tabi nwọn ba hu iwa ti ko tọ wa lọrun si wa tabi si elomiran, ẹ jẹ ki a mu suru, ki a si ṣe alaye fun awọn ọmọ na pẹlu ahọn tutu pe, irufẹ iwa bayi ko dara, Ki a si fun wọn ni ẹkọ ati imọran lori irufẹ iwa ti o dara ti yio si ṣe wọn ni anfani lati ma hu.

Awọn obi miran a ma a bu awọn ọmọ wọn ti o ba ṣe aṣiṣe, ni olori buburu, ni ọmọ ẹran, ni afọri, ni alakọri, ni ọmọ eṣu ati bẹlẹ.

Mo fẹ ki [illegible] o si ye awọn obi yekeyeke pe, oruko ti a ba fi binu sọ ọmọ wa ni ọmọ wa ni yio jẹ Ọlọrun maṣe jẹ ki awọn ọmọ wa jẹ oruko buburu Anabi (Ki ike ati ọla ma a ba a titi lailai Amin pupọ) emase jẹ ki awọn ọmọ wa gba oruko buburu Ami.

Ẹjẹ ki a ma a sọ awọn ọmọ wa ni oruko ire, Ẹsi jẹ ki ama gba adura fun wọn ni gbogbo igba pe, ki wọn jẹ ọmọ olori re, ki wọn jẹ ọmọ ti yio fẹran ẹsin ti ẹsin yio rọ lọrun gẹgẹ bi Anabi wa (Salahla hu wa salam).


Ọmọ Kekere Jojolo

Suru ati iyanju ati adura ni gbogbo igba ni yio ṣe iranwọ fun wa ati fun awọn ọmọ wa lati di ọmọ ire. Ọpọlọpọ awọn obi ti wọn ko ni suru ba awọn ọmọ wọn lọ ni wọn nkẹ abamọ lọwọlọwọyi.

Nwọn ti le awọn ọmọ wọn si ti di ẹhanna awọn ti [illegible] ti wọn [illegible] yi [illegible] ọmọ ire wọn.

Ẹ maṣe ṣe ahun si awọn ọmọ yin [illegible] ki wọn [illegible]. Eni ba ṣe ahun si ọmọ rẹ, yio si tẹ lọwọ ọmọ rẹ [illegible]. A ki i si se ahun [illegible] si gbayi. Ahun [illegible] si aiye [illegible] Alamọri ahun ki i dara

Bi ẹ ba gbiyanju ti ẹ se inawo ẹkọ dada fun awọn ọmọ nyin, ti ẹ si ṣe suru fun wọn ni ẹkọ ile, ti Ọlọrun si ran ayia lọwọ, ti o jẹ ki wọn gbọ ki wọn si gba, nwọn yio si ma a fi igbadun ṣe ayọ lọla, pẹlu ogo Oluwa.

Irọrun awọn ọmọ nyin, anfani ati ayọ tiyin.


Alhaji Y. A. Disu

Oluwa rere gbawa, maṣe fun wa ni awọn alaigbọran ọmọ ti eṣu yio jẹ lere. Amin o.

---

Lati Oju Ewe Keji

salọ Ọgbẹni Chukuma sisọ pe nwọn si mu Dọkita Obi laiti iwe ẹsun mu.

Ki Adajọ to sun asiko idajọ siwaju Oloye Rotimi Williams si sọ ninu ọrọ rẹ pe ko si ẹsun ofin kan to a gari ti Ọlọpa wa fi kan Dọkita Obi ki o to mu ati pe gbogbo ọrọ rẹ lo si kuna patapata. Oloye Williams si tun sọ pe Ọlọpa na le ni eto lati mu Dọkita Obi lai sọ iru ẹsun to fi kan fun un

Oloye Williams si tun fi ye ile ẹjọ na lati kọ gbogbo ọrọ Ọlọpa na laijẹ pe o mu Ọgbẹni John Lynn to sọ pe on lo ran on lati lọ mu Dokita Obi lati wa jeri fun ọrọ na,

Ọgbẹni Jinadu ti o jẹ agbẹjọro ijọba sọ Dokita Obi lo ni ẹtọ lati ṣe gbogbo awọn nkan iru bẹ ki ẹjọ na to bẹrẹ

Agbẹjọro na si tun fi ye ilẹ ẹjọ pe dida ti nwọn da Dokita Obi si'ẹ fun iditẹ si Ijọba ko fi han pe nwọn si ti da silẹ patpata. ọgbẹni jinadu si tun sọ nigbati on wo gbogbo ẹsun ti nwọn fi kan Dọkita Obi, oni on ko ri ẹsun irira ninu gbogbo ẹsun na. Ọgbẹni Jinadu si tun sọ pe alaifi iwe ẹsun mu Dokita Obi pe nyẹn ko si le mu irira wa rara,

Ọgbẹni Jinadu si tun sọ si pe Ọgbẹni Chukwuma si iṣe Olujẹjọ ijọba ati pe ohun to si ba ofin lọ lo ki tẹlẹ.


make it a successful
SEASON
with MERCEDES-BENZ
TRUCKS

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.
LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN,
KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA
PORT-HARCOURT & ABA.

# IROHIN IMOLE

IMỌLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 700 THURSDAY, MAY 21, 1964 (2D)


## Obinrin Kan gun Ọkọ Rẹ L'ọbẹ

GUSAU:— Jinnijinni dabo gbogbo enia n'gbati awọn enia joko ninu ile Obinrin kan si sare wọle ti o le gbogbo awọn ọrẹ Ọkọ rẹ sita ti o nbi ọkọ rẹ lere ọrọ, ti ọrọ na si di ohunti i wọn nja, nigbati awọn ara ile yio fi sare si ilẹkun pẹlu ipa Obinrin na ti gun ọkọ rẹ ni ọbẹ ni pari ẹrẹkẹ ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi.

Ẹniti ọrọ na ṣoju rẹ fi ye Oniwe Irohin wa pe, Obinrin na ko ti ko wa si ile ọkọ rẹ, sugbon a ma a wa si ọdọ Ọkunrin na, ti o ba ṣe ọjọ meji tabi mẹta a tun pada lọ si ile wọn.

Sugbọn nigbati "Iyawo pankeke" yi de ni ọjọ na, are lo sa wọle lọba ọkọ rẹ, awọn alejo kan ti nwọn tilẹ wa ni ọdọ ọkọ rẹ nigbana, o paṣẹ pe ki gbogbo wọn jade, ki wọn fun on ni iṣẹju meji pere, ti awọn ba ṣetan, ki wọn wọle. awọn enia na si jade, ni o ba tilẹkun,

Ṣugbọn ko pẹpupọ lẹhin eyi, ti awọn enia na ngbọ ti igba nlu igba, ti awo tanngasan si nrefọ loke ni wọn ba sare wọle ṣugbọn ninu agbara ẹjẹ ni wọn ba Ọkunrin na, iyawo rẹ ti gun un lọbẹ, ti nwọn ti fẹ gbelọ si ile-iwosan ni Ọkunrin na ba ku.

Lẹsẹkẹsẹ ni wọn mu Obinrin na lọwọ pe ko gbọdọ salọ, won si lọ pe Ọlọpa wa. Awọn Ọlọpa ti gbe oku Ọkunrin na lọ si ile - Iwosan wọn ti mu Obinrin na lati ṣe iwadi ọrọ lọwọ rẹ.

# EJO LE ONIWASU KAN JADE NINU ṢỌỌṢI !

## Awọn Ọmọ Ijọ Bẹlugbẹ !!

ABAKALIKI :- Ọrọ di pẹntuka, gbogbo en a si bẹrẹsi sare Ọlọmọ gb'ọmọ pọn nigbati Oniwasu fẹ bọ sinu apoti lati lọ ba awọn ọmọ Ijọ sọrọ ti o si sare jade ninu apoti iwasu ti o nkigbe "ejo! ejo!! ejo!!!" ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi.

Irohin awọn Ọlọpa-Ijọ na fi ye wa pe, awọn ti bẹrẹ isin awọn lati agogo marun irọlẹ, ki awọn si pari rẹ ni deede agogo mẹfa nitoripe ko si ina fun awọn lati ṣe isin.

Nigbati awọn gbadura ti awọn si kọrin tan, ni oniwasu ba ni ki on bọ sinu apoti iwasu lati lọ fi "onjẹ ẹmi" bọ awọn ọmọ Ijọ, bi o si ti ṣi Bibeli ti o fẹ ma a ka a, ni ojiji lo sare jade ti osi nkigbe "ejo! ejo!! ejo!!!".

Igbe ila lfẹlewe.!!okoila fẹ ilasa, ni gbogbo Ṣọọṣi ba daru, ti ọrọ si di—boolọ o ya fun mi. Awọn ọmọ Ijọ miran mu iwe nwọn ko ranti gbe Bibeli wọn, awọn miran gbe Bibeli, nwọn ko ranti iwe Orin, ẹniti o gbe apamọwọ wa gbagbe rẹ silẹ, ẹniti o fi digi bo oju ko mọ igbati digi bọ sọnu lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo ijọ si tuka yanga

Lojukanna ni awọn enia ti lọ sure pe baba ọdẹ kan ti o wa nitosi, nigbati baba ọdẹ na de' o wọ inu ṣọsi na lọ o si pa ejo na. Nigbati o gbe jade ni gbogbo awọn ọmọ ijọ na ba ri ejo sebe nla dudu rẹrẹ na ti o fẹrẹ to ojola. Nigbati baba-Ọdẹ na pa ejo na tan o gbe lọ si ile rẹ lati lọ seitọju rẹ ni oniwasu ba pe awọn ọmọ Ijọ pe ki awọn pari isin sugbọn bi o ti bẹ awọn ọmọ Ijọ na to ẹnikan ko wole ninu wọn ti wọn fi tuka lọ si ile wọn pe eyiti a se loni yi to, ẹ jẹki o si tun di ọjọ isimi ti mbọ ni gbogbo wọn ba tuka.

## Adenrele L'ọmọ Na Njẹ

EKO:— Irohin ko to afojuba ni inawo isọmọloruko ti Ọmọ-Ọba Adeniran Adefarakan, ẹniti a mọ adape oruko rẹ ni "ẸRUKOBODO" ninu ile rẹ ni No 8, Idumagbo Avenue l'Eko, ni owurọ kutu ọjọ Alaruba ti iṣe ogunjọ oṣu May 1964, fun "Ọmọ-kekere alejo aiye" ti Oluwa fi ta on ati iyawo rẹ Ashabi Adebayọ lọrẹ.

Lẹhin eto iṣẹdalẹ ati lẹhin isin ti awọn Musulumi Imam Ọrẹofẹrọ sọ Orukọ ọmọ na ti „Mọgaji" ile Ọba Olubuṣe fi ransẹ lati Ile-Ifẹ jade si eti gbọ awọn Alufa ati awọn enia, jankanjankan ọmọ Ile-Ifẹ to peju pesẹ sibi isin nwọn sọ ọmọ na ni :—

MỌNSURAT ALAKẸ ADENRELE ADEFARAKAN.

Diẹ ninu orukọ awọn gbajumọ to peju sibi isin iṣọmọ lorukọ na ti a raye lati darukọ wọn ninu irohin yi ni-: Ọmọ Ọba Tunde-Adefarakan Ọmọ Ọba Shijuade, Ọmọ Ọba Shubulade Adefarakan Ninilade Adefarakan. Oloye D B. B. Omoaji. Phillip Arawumi Salami Wotunde Abasi Ọgẹdi Karimu Lawal Tọyọbọ Amọri Adeọla Onikoyi SalamiAkanbi Silifatu Ọmọshoriwa

Irohin Imọlẹ ki Ẹrukobo do ku orire ki Oluwa da Ọmọ na si ko mase fi la iya rẹ loju.


it beats...
as it sweeps...
as it cleans...



The NEW de luxe
HOOVER cleaner
Buy yours NOW at:
LEVENTIS TECHNICAL
New showrooms at Iddo, Marina & Mainland Stores, Kingsway, P.Z., U.T.C. Stores and also throughout our branches in Nigeria.



Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor:- TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos 21/5/64